اتحاد علماء افريقيا
UNION OF AFRICAN MUSLIM SCHOLLARS
UNION DES ULEMAS D'AFRIQUE

# نواقض الإسلام

## سماحة الشيخ عبد اللّه بن عبد العزيز بن باز رحمه الله

قام بترجمته إلى اليوروبا

## الأستاذ حبيب اللّه بن عبد الرحمن الأيدوي

# *ÀWỌN OHUN TÍ Ó MÁA Ń BA ẸSÌN ISLĀM JẸ́*

*LÁTI ỌWỌ́:*

***ASH-SHAYKH* ‘ABDUL-‘AZĪZ BN ‘ABDILLĀH BN BĀZ**

*ÌTUMỌ̀ SÍ YORÙBÁ:*

***Habībullāh Bn AbdirRahmān Al-Edewī***

طبع على نفقة وصية خولة دخيل الجسار رحمها الله (دولة الكويت) بإشراف اتحاد علماء إفريقيا

**A tẹ̀ ẹ́ jáde pẹ̀lú ìnáwó *Waṣiyyah Khawlah Dakhīl Al-Jassār,* kí Ọlọ́hun kẹ́ ẹ, (Orílẹ̀-Èdè *Kuwait*) ní abẹ́ àmójútó Ìṣọ̀kan àwọn Àlùfáà Áfíríkà**

2016/1437

## ÀWỌN OHUN TÍ Ó MÁA Ń BA ẸSÌN *ISLĀM* JẸ́ [1]

Gbogbo ọpẹ́ àti ẹyìn ti Ọlọ́hun Allāh ni í ṣe. Kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá ẹni tí kò sí Ànábì mìíràn lẹ́yìn rẹ̀, àwọn ará ilé rẹ̀, àwọn sàábé rẹ̀, àti ẹnikẹ́ni tí ó bá tẹ̀lé ìlànà rẹ̀.

Lẹ́yìn náà, ìrẹ Mùsùlùmì! Lọ mọ̀ pé dájúdájú Ọlọ́hun Allāh, mímọ́ ni fún Un, ṣe wíwọ inú ẹ̀sìn *Islām,* dídìrọ̀ mọ́ ọn, àti ṣíṣọ́ra fún ohun tí ó yapa rẹ̀ ní ọ̀ranyàn lórí gbogbo àwọn ẹrúsìn (Rẹ̀). Ó sì gbé Ànábì Rẹ̀ Muḥammad -kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a- dìde láti pèpè lọ síbi eléyìí. Ó (Ọlọ́hun), Ọba Abiyì tí Ó gbọngbọ́n, sì fún wa níròò pé ẹnikẹ́ni tí ó bá tẹ̀lé e, níti pàápàá, ti mọ̀nà. Ẹnikẹ́ni tí ó bá sì ṣẹ́rí kúrò lọ́dọ̀ rẹ̀ ti sọnù. Ó (Ọlọ́hun) sì wá (àwọn ẹrúsìn Rẹ̀) ní ìṣọ́ra, nínú àwọn *'āyah* (ẹsẹ *Al-Qur'ān*) tí ó pọ̀, kúrò níbi àwọn okùnfà ìkómọ̀ kúrò nínú ẹ̀sìn *Islām*, àti gbogbo àwọn ìran ẹbọ àti àìgbàgbọ́. Àwọn onímímọ̀ -kí Ọlọ́hun kẹ́ wọn- ṣàlàyé, níbi àkòrí ọ̀rọ̀ nípa ìdájọ́ ẹni tí ó kómọ̀ kúrò nínú ẹ̀sìn *Islām,* pé Mùsùlùmì le kómọ̀ kúrò nínú ẹ̀sìn rẹ̀ pẹ̀lú oríṣiríṣi àwọn ohun tí ó máa ń ba ẹ̀sìn *Islām* jẹ́ tí ó pọ̀. Eléyìí tí yóò sọ ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ àti dúkìá rẹ̀ di ẹ̀tọ́ (yóò sọ ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ di ẹ̀tọ́ láti dà sílẹ̀, yóò sí sọ gbígbé ẹsẹ̀ lé dúkìá rẹ̀ di ẹ̀tọ́ fún ìjọ̀ba *Islām*), yóò sì sọ ọ́ di ẹni tí ó jáde kúrò nínú ẹ̀sìn *Islām.* Nínú èyí tí ó léwu jù nínú rẹ̀, tí ó sì sábà máa ń ṣẹlẹ̀, ni àwọn ohun mẹ́wàá kan tí ó máa ń ba ẹ̀sìn *Islām* jẹ́ tí *Ash-shaykh Al-Imām* Muḥammad ọmọ 'Abdil-Wahhāb àti àwọn onímímọ̀ mìíràn -kí Ọlọ́hun kẹ́ gbogbo wọn- sọ. A ó sọ wọ́n fún ọ ní ṣókí nínú ohun (àlàyé) tí ó ń bọ̀ yìí, nítorí kí o le ṣọ́ra fún wọn, kí o sì kìlọ̀ fún elòmíràn nípa wọn, níti ìrankàn ọlà àti àláàfíà kúrò nínú wọn pẹ̀lú àwọn àlàyé kékeré tí a ó sọ lẹ́yìn (mímẹ́nu bà) wọn.

**ÀKỌ́KỌ́:** Nínú àwọn ohun mẹ́wàá tí ó máa ń ba ẹ̀sìn *Islām* jẹ́ ni: Ṣíṣe ẹbọ níbi ìjọsìn fún Ọlọ́hun. Ọlọ́hun Ọba tí Ọlá Rẹ̀ ga sọ wí pé:

> **"Dájúdájú Ọlọ́hun kì í ṣe àforíjìn kí á ṣe ẹbọ pẹ̀lú Rẹ̀, ṣùgbọ́n Ó máa ń ṣe àforíjìn ohun tí kò tó eléyìí fún ẹni tí Ó bá fẹ́".**[2]

Ọlọ́hun Ọba tí Ọlá Rẹ̀ ga tún sọ wí pé:

> **"Dájúdájú ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣe ẹbọ pẹ̀lú Ọlọ́hun, dájúdájú Ọlọ́hun ti ṣe ọgbà-ìdẹ̀ra (*Al-Jannah*) ní èèwọ̀ fún un, àti pé iná ni ibùgbé rẹ. Kò sì sí aláràǹṣe kankan fún àwọn alábòsí".**[3]

Nínú rẹ̀ ni pípe àwọn òkú, wíwá ìrànlọ́wọ́ kúrò nínú ewu pẹ̀lú wọn, jíjẹ́jẹ̀ẹ́ fún wọn, àti pípa ẹran fún wọn.

**ÈKEJÌ:** Ẹnikẹ́ni tí ó bá fi àwọn alàgàta sí ààrin òun àti Ọlọ́hun, tí ó ń pè wọ́n, tí ó sì ń tọrọ ìṣìpẹ̀ lọ́dọ̀ wọn, tí ó sì ń gbára lé wọn, dájúdájú onítọ̀hún, pẹ̀lú àpanupọ̀ àwọn onímímọ̀, ti ṣe àìgbàgbọ́.

**ÈKẸTA:** Ẹni tí kò bá gbà pé kèfèrí (aláìgbàgbọ́) ni àwọn ọ̀ṣẹbọ, tàbí ó ṣe iyèméjì nípa ìjẹ́-kèfèrí wọn, tàbí ó gbà pé ìlànà wọn ní dára, ẹni náà ti di kèfèrí.

**ÈKẸRIN:** Ẹni tí ó bá ní àdìsọ́kàn pé ìlànà ẹlòmíràn yàtọ̀ sí ti Ànábì -kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a- pé ju ìlànà rẹ̀ lọ, tàbí pé ìdájọ́ ẹlòmíràn yàtọ̀ sí tirẹ̀ dára ju ìdájọ́ rẹ̀ lọ, gẹ́gẹ́ bíi àwọn tí wọn máa ń gbé ọlá fún ìdájọ́ àwọn òrìṣà lórí ìdájọ́ rẹ̀, kèfèrí ni ẹni náà.

**ÈKARÙN-ÚN:** Ẹni tí ó bá kórìíra nǹkankan nínú ohun tí Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun -kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a- mú wá, kódà kí òun gan-an alára mún un lò, dájúdájú ó ti di kèfèrí. Nítorí ọ̀rọ̀ Ọlọ́hun Ọba tí Ọlá Rẹ̀ ga tí Ó sọ wí pé:

[1] Àtẹ̀jáde àkòrí yìí wáyé nínú ìwé-ìròyìn *Al-buḥūthul-'Islāmiyyah* ní Riyāḍ, òǹkà keje eléyìí tí ó jáde ní oṣù; *Rajab, Sha'bān, Ramaḍān* àti *Shawāl* ọdún 1403 A.H.

[2] *Sūratun-Nisā'*: 116.

[3] *Sūratul-Mā'idah*: 72.

**“Ìyẹn jẹ́ bẹ́ẹ̀, nítorí pé wọ́n kórìíra ohun tí Ọlọ́hun sọ̀kalẹ̀, nítorí náà Ó (Ọlọ́hun) ba iṣẹ́ wọn jẹ́”.**[4]

**Ẹ̀KẸFÀ:** Ẹni tí ó bá fi nǹkankan nínú ẹ̀sìn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun -kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a-, tàbí ẹ̀san rẹ̀ tàbí ìjìyà rẹ̀ ṣe yẹ̀yẹ́, ti di kèfèrí. Ẹ̀rí rẹ̀ ni ọ̀rọ̀ Ọlọ́hun Ọba tí Ọlá Rẹ̀ ga tí Ó sọ wí pé:

**“Wí pé: Ṣé Ọlọ́hun àti àwọn Àmí Rẹ̀ àti Ìránṣẹ́ Rẹ̀ ni ẹ fi ń ṣe yẹ̀yẹ́? Ẹ má ṣe wá àwáwí, dájúdájú ẹ ti ṣe àìgbàgbọ́ lẹ́yìn ìgbàgbọ́ yín”.**[5]

**ÈKEJE:** Idán pípa; nínú rẹ̀ ni àsàsí kí ọkọ àti ìyàwó kórìíra ara wọn àti òògùn ìfẹ́, ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣe é tàbí ó yọ́nú sí i, ti di kèfèrí. Ẹ̀rí rẹ̀ ni ọ̀rọ̀ Ọlọ́hun Ọba tí Ọlá Rẹ̀ ga tí Ó sọ wí pé:

**“Ṣùgbọ́n wọn kò ní kọ́ ẹnìkankan ní (idán) títí tí wọn yóò fi sọ pé: Dájúdájú àwa kò jẹ́ nǹkankan bíkòṣe àdánwò, nítorí náà má ṣe àìgbàgbọ́”.**[6]

**Ẹ̀KẸJỌ:** Ṣíṣè àtìlẹ́yìn fún àwọn ọ̀ṣẹbọ àti ríràn wọ́n lọ́wọ́ lórí gbígbé ogun ti àwọn Mùsùlùmí, ẹ̀rí rẹ̀ ni ọ̀rọ̀ Ọlọ́hun Ọba tí Ọlá Rẹ̀ ga tí Ó sọ wí pé:

**“Àti pé ẹnikẹ́ni tí ó bá mú wọn ní olùgbọ̀wọ́ nínú yín; dájúdájú òun náà ti wà lára wọn. Dájúdájú Ọlọ́hun kò ní fi ọ̀nà mọ àwọn alábòsí èniyàn”.**[7]

**ẸKẸSÀN-ÁN:** Ẹni tí ó bá di àdìsọ́kàn pé ìgbàláàyè wà fún apákan nínú àwọn èniyàn láti jáde kúrò nínú òfin ẹ̀sìn Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Muḥammad -kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a-, ẹni náà ti di kèfèrí. Nítorí ọ̀rọ̀ Ọlọ́hun Ọba tí Ọlá Rẹ̀ ga tí Ó sọ wí pé:

**“Àti pé ẹnikẹ́ni tí ó bá wá ohun mìíràn ní ẹ̀sìn yàtọ̀ sí ẹ̀sìn *Islām*, a kò ní gbà á lọ́wọ́ rẹ̀, àti wí pé ní Ọ̀run yóò wà nínú àwọn ẹni òfò”.**[8]

**ẸKẸWÀÁ: G**ígúnrí kúrò níbi ẹ̀sìn Ọlọ́hun, kò ní kọ́ ọ, kò sì ní mún un lò, ẹ̀rí rẹ̀ ni ọ̀rọ̀ Ọlọ́hun  Ọba tí Ọlá Rẹ̀ ga tí Ó sọ wí pé:

**“Àti pé tani ó ṣe àbòsí tó ẹni tí a fi àwọn Àmì Ọlọ́hun Ọba rẹ̀ rán létí, lẹ́yìn náà tí ó wá gúnrí kúrò níbẹ̀? Dájúdájú Àwa yóò gbẹ̀san lára àwọn ọ̀daràn”.**[9]

Kò sí ìyàtọ̀ níbi gbogbo àwọn ohun tí ó máa ń ba ẹ̀sìn *Islām* jẹ́ yìí láàrin ẹni tí ń ẹ̀fẹ̀, ẹni tí ó mọ̀ọ́mọ̀, àti ẹni tí ń bẹ̀rù àyàfi ẹni tí wọ́n bá jẹ nípá. Gbogbo wọn sí wà nínú ohun tí ewu rẹ̀ tóbi jùlọ, tí ṣíṣẹlẹ̀ rẹ̀ sí wọ́pọ̀ jùlọ. Nítorí náà ó pàtàkì fún Mùsùlùmí kí ó ṣọ́ra fún wọn, kí ó sì máa páyà wọn lórí ẹ̀mí ara rẹ̀. A wá ìṣọ́ pẹ̀lú Ọlọ́hun kúrò níbi àwọn okùnfà ìbínú Rẹ̀, àti ìyà ẹlẹ́ta-eléro Rẹ̀. Kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá ẹni tí ó dára jùlọ nínú àwọn ẹ̀dá Rẹ̀, Muḥammad, àwọn ará ilé rẹ̀, àti àwọn sàábé rẹ̀. Ọ̀rọ̀ rẹ̀ (*Ash-shaykh* Muḥammad ọmọ ‘Abdil-Wahhāb) -kí Ọlọ́hun kẹ́ ẹ- parí síbí.

---

[4] *Sūratu Muḥammad*: 9.
[5] *Sūrat-Tawbah:* 65, 66.
[6] *Sūratul-Baqarah:* 102.
[7] *Sūratul-Mā’idah*: 51.
[8] *Sūratu ’Āli-’Imrān* : 85.
[9] *Sūratus-Sajdah* : 22.

Nínú ohun tí ó wọnú ìpín kẹrin ni: Ẹni tí ó bá di àdìsọ́kàn pé àwọn ètò àti àwọn òfin tí àwọn ènìyàn ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ lọ̀lá ju òfin ẹ̀sìn *Islām* lọ, tàbí pé ó ṣe déédé pẹ̀lú rẹ̀, tàbí pé ó lẹ́tọ̀ọ́ kí á wá ìdájọ́ lọ síbẹ̀ kódà kí ó gbàgbọ́ pé dídájọ́ pẹ̀lú òfin ẹ̀sìn *Islām* ni ó lọ̀lá julọ, tàbí pé ìlànà ẹ̀sìn *Islām* kò ṣe lò ní àsìkò ọ̀làjú titun ayé òde-òní, tàbí pé ohun ni ó kó ìfàsẹ́yìn bá àwọn Mùsùlùmí, tàbí pé àjọṣepọ̀ ènìyàn pẹ̀lú Ọlọ́hun Ọba nìkan ni ó ní í ṣe pẹ̀lú, láìdásí àwọn ọ̀ràn ìṣẹ̀mí ayé mìíràn.
Nínú ohun tí ó tún wọnú ìpín kẹrin ni: Ẹni tí ó bá gbàgbọ́ pé lílo ìdájọ́ Ọlọ́hun nípa gígé ọwọ́ olè, tàbí sísọ adélébọ̀ tí ó ṣe àgbèrè lókò pa, kò bá àsìkò yìí mu. Nínú ohun tí ó tún wọnú rẹ̀ ni: Ẹnikẹ́ni tí ó bá ní àdìsọ́kàn pé dídájọ́ pẹ̀lú ohun (ìdájọ́ àgbélẹ̀rọ) tí ó yàtọ̀ sí òfin ẹ̀sìn Ọlọ́hun, níbi àjọṣepọ̀ láàrin àwọn ènìyàn, tàbi lórí àwọn ìjìyà-ẹ̀ṣẹ̀ eléyìí tí Ọlọ́hun là kalẹ̀ lórí àwọn ìran ẹ̀ṣẹ̀ kan, tàbí ohun mìíràn yàtọ̀ sí méjèèjì lẹ́tọ̀ọ́ fún lílò, kódà kí ó má ní àdìsọ́kàn pé ìyẹn (ìdájọ́ àgbélẹ̀rọ náà) lọ̀lá ju ìdájọ́ òfin ẹ̀sìn *Islām* lọ. Nítorí pé pẹ̀lú èyí, ní àpanupọ̀ àwọn onímímọ̀, a jẹ́ pé ó ti ṣe ohun tí Ọlọ́hun pè ní èèwọ̀ ní ẹ̀tọ̀ nìyẹn. Gbogbo ẹni tí ó bá sì ti ṣe ohun tí Ọlọ́hun pè ní èèwọ̀ ní ẹ̀tọ̀, nínú àwọn ohun tí mímọ̀ rẹ̀ pọndandan nínú ẹ̀sìn, bíi àgbèrè ṣíṣe, ọtí mímu, jíjẹ owó-èlé, àti dídájọ́ pẹ̀lú ohun tí ó yàtọ̀ sí òfin ẹ̀sìn Ọlọ́hun, kèfèrí ni ẹni náà pẹ̀lú àpanupọ̀ àwọn Mùsùlùmí.

À ń bẹ Ọlọ́hun Allāh kí Ó fi gbogbo wa lápapọ̀ ṣe kòǹgẹ́ ohun tí ó yọ́ Ọ nínú, kí Ó sì fi wá mọ̀nà àti gbogbo Mùsùlùmí lọ sí ojú-ọ̀nà Rẹ̀ tí ó tọ́, dájúdájú Òun ni Olùgbọrọ̀, Ẹni tí Ó súnmọ́. Kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá Ànábì wa Muḥammad